# IROHIN IMOLE

IMOLẸ ORẸ AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No 722 THURSDAY JUNE, 18, 1964 (2D)


## Ọkunrin kan Fi Gbese Lé Iyawo Rẹ Lọ

AKURẸ:- Ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi ni Iyawo ile kan, Iyaafin Juliana Adeṣọla Akinrinṣọla ti o nṣiṣẹ Olukọ pe Ọkọ rẹ lẹjọ ikọsilẹ lori ẹsun iwa ika, inakuna ati gbese.

Obinrin na ṣe alaye pe, ninu Ọdun 1955 ni on ati ọkọ on ṣe igbeyawo alarinrin, Ọlọrun si ti pese ọmọ mẹta fun awọn Ọkunrin meji Obirin kan.

Ṣugbọn lati inu ọdun 1961, ni ọkọ on ti bẹrẹ sii ijẹ gbese, ki iṣe ọdọ awọn enia nikan ṣugbọn awọn Oyinbo oniṣowo pẹlu ti nwọn si ma a nwalẹ wa yọ on ati ọkọ on lẹnu. Nigbati ọran na kọkọ bẹrẹ bi ẹnikan ba wale wa sin gbese, on fun oluwarẹ ṣugbọn bi on ti nsan gbese na bẹni ọkọ on tun nlọ jẹ gbese miran

O tun ṣe alaye pe lati igbana, gbese ni on nfi owo oṣu on san, ti on kosi ni owo lọwọ. Nigbati ọrọ na su on, on pe awọn enia rẹ, nwọn so fun nu ṣugbọn ko yipadaon si kolọ si ile awọn Baba on

Obinrin na wa rọ ile ẹjọ pe ki o tu igbeyawo awọn mejeji ka, ni adajọ ba tu igbeyawo na ka nigbati ọkọ gba pe otitọ ni ẹjọti iyawo on ro niwaju adajọ Adajọ si paṣẹ pe ki Ọkunrin na lọ san pọnun mẹrindilọgbọn (£26 ) fun Iyawo rẹ awọn mejeji si tuka.

# IJỌBA GBA LATI SAN ẸKUNWO OWO-OṢU FUN AWỌN OṢIṢẸ

EKO:— Gbogbo awọn oṣiṣẹ Ijọba ati ti awọn Oyinbo Oniṣowo gbọ irohin idunnu kan pe, Apapọ Ijọba Naijiria ti gba lati san ẹkunwo-owo - oṣu fun gbogbo awọn oṣiṣẹ orilẹ-ede yi.

Ni ọjọ kini oṣu yi ni awọn oṣiṣẹ orilẹ-ede yi binu da iṣẹ silẹ ti gbogbo wọn ko si ṣiṣẹ mọ.

Awọn oṣiṣẹ na fa aṣọ wọn ya, nwọn si fi ẹsẹ janlẹ, nwọn si tun da họ ọ si Apapọ Ijọba nigbati o kọ lati gba imọran oluwadi Igbimọ Morgan ti o paṣẹ pe ki Ijọba fi owo ti o gbe pẹ diẹ si owo oṣu awọn oṣiṣẹ.

Ṣugbọn nigbati awọn oṣiṣẹ ti da iṣẹ silẹ fun odidi ọjọ mẹrinla ni Apapọ Ijọba ti gba pe ki awọn oṣiṣẹ lọ bẹrẹ iṣẹ, ki awọn ati awọn aṣiwaju ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ bẹrẹ si jiroro lori ọrọ ẹkunwo-owo Oṣu na.

Lẹhin eyi ni Igbimọ Apapọ Ijọba wa yan Oloye Festus Okotiẹ-Ẹbọh, Minista Alamojuto eto inawo fun Apapọ Ijọba lati lọ ṣe ('eto na lerin Ijọba ati awọn oṣiṣẹ.

Bekanna ni Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria da imọran pe ki Dokita K. O. Mbadiwe Minista Alamojuto igbokegbodo ọkọ Ofurufu fun Apapọ Ijọba Naijiria Oloye J. M. Johnson Minista Alamojuto eto iṣẹ ati alafia ilu Ọgbẹni J.C. Ọbande Minista Alamojuto eto idasilẹ iṣẹ ati Alhaji Wasiri Ibrahim Minista Alamojuto eto owo ati Iṣẹ aje fun Apapọ Ijọba Naijiria o lọ ṣe oluranlọwọ ninu ipade na fun oloye Okotiẹ-Ẹbọh.

Ni deede agogo ma run irọlẹ ana ni gbogbo awọn enia na, eyi ni awọn Alaṣẹ Apapọ Ijọba, awọn Oyinbo oniṣowo, awọn Alaga Ile-iṣẹ Aje ati awọn Asiwaju ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ.

Nigbati eto na bẹrẹ ni awọn. Oloye Festus Okotiẹ Ẹbọh lọ ṣe Alaga. Bi ipade na ti bẹrẹ ni Oloye na dide lori aga ijoko rẹ ninu ẹwu agbada funfun pẹlu fila "Awo" pupa ti o de lori.

Bi ipade na ti bẹrẹ ti Oloye Okoti-Ẹbọh si sọrọ tan, ni Alhaji Haruna Popoọla Adebọla ba dide duro ti o si ba awọn enia na sọrọ.

Ninu ọrọ rẹ, Alhaji Adebọla ni, o jẹ ohun ẹdun ọkan lati sọ fun Igbimọ ijoko na pe awọn ti bẹrẹsi iri ohun iyanu, eyiti o yatọ patapata si ipinnu ti awọn Aṣiwaju ẹgbẹ Oṣiṣẹ ba Ijọba ṣe ki awọn to pada si ẹnu iṣẹ awọn.

Alhaji Adebọla wa ṣe alaye pe, ọpọlọpọ awọn Oṣiṣẹ ni nwọn ti wa nsọ fun awọn pe, awọn Ọga Ile iṣẹ awọn ti bẹrẹsi "halẹ" mọ awọn pe awọn fẹ da awọn duro lẹnu iṣẹ.

Alhaji Adebọla ni ọrọ na ya awọn lenu awọn si fẹ gbo lati ọdọ Ijọba bi ko ba lodi si ofin pe ẹnikan tapa si Apapọ Ijọba. Ṣugbọn Oloye Okotiẹ-Ẹbọh, ti iṣe Alaga ipade na rọ awọn Asiwaju ẹgbẹ oṣiṣẹ lati fi ọrọ na silẹ fun on, ki on wadi kẹtẹkẹtẹ idi ọrọ na, Bi on ba si ri okodoro idi ọrọ na ti o ba jẹ otitọ, on yio ṣe eto ti o ba yẹ fun iru awọn Oyinbo onisowo na. Gbogbo wọn si gba pe ki Okotie-Ẹbọh ṣe iwadi ọrọ na.

Nigbati gbogbo wọn ti gba ọrọ na tan ni nwọn wa bẹrẹsi ba ipade wọn lọ.

Oniwe irohin wa ti o lọ sibi ipade na fi ye wa pe, gbogbo awọn Ijọba Ipinlẹ ni nwọn ran Minista Alamojuto eto inawo wọn wa sinu ipade na.

Ọba C. D. Akran, Minista Alamojuto eto inawo fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun lo ṣe asiwaju awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun wa sinu ipade na.

Nigbati Oloye Okotiẹ — Ẹbọh sọrọ tan, ni o wa kesi Dokita K. O. Mbadiwe, ẹniti iṣe Agbọrọsọ Apapọ Ijọba, o si ṣe alaye ohunti Ijọba nro ati iṣẹ ti Apapọ Ijọba fẹ ṣe fun awọn oṣiṣẹ lati kọ ile abọọde fun wọn lati ma a gbe eyiti yio fun wọn ni irọrun ti yio si na wọn lorun ni asanisantan owo ile, eyiti o da ẹru pa ọpọlọpọ awọn oṣiṣẹ o tun ṣe alaye pe, nigbati awọn oṣiṣẹ ba denu ile na tan, Ijọba yio ma gba owo ile na lọwọ wọn, nigbati owo na ba si pe, ile na yio di ti awọn oṣiṣẹ.

Lehinti Dọkita Mbadiwe sọrọ tan, ni Oloye Okotiẹ-Ẹbọh wa kesi Minista Alamojuto eto inawo fun Ijọba Ipinlẹ Ariwa ẹniti o dupẹ lọwọ gbogbo

Wo Oju Ewe Kini



Oloye Festus Okotiẹ - Ẹbọh
"Omimi Ejo"



Dọkita K. O. Mbadiwe
Minista Alamojuto Igbokegbodo Ọkọ Ofurufu

# ITAN AJIRAN ILU AWỌN OKU ( Apa 19 )

**Lati Ọwọ J. O Shoyinka**

Ibiti mo ba ọrọ mi de ni yi Gẹgẹbi ileri wọn, tijo ba Elegbede ni o la Ogbojuleogun mọlẹ ni nwọn yio bẹ wọn lori patapata, ṣugbọn ki se se mọ. Nwọn bẹrẹ si fi agbara se wọn lalejo, nwọn ny. wọn si ko pẹ ọjọ ti o tẹle ni Ajọdun Ẹnikẹni ti o ba jẹ ọmọ jire ti mọ pe elegun ni Ijimare.



AWORAN YI NI AJIRAN ILU AWỌN OKU

Awọn Egun bẹrẹ si pidan Oba ati awọn ọmọ Onilogbo ga ganga, nwọn nwo—rae. Awọn Ijimare yi ede wọn pada, ko si ẹniti o gbọ ọ mọ. afi Ogbojuleogun nitoripe o ti nba awọn ẹranko gbe inu igbo ri. Nwọn o ba ara wọn sọ pe ti ọkan ninu wọn ba di Ojola, ki o lọ mọ awọn ọmọ Onilogbo ki osi fun wọn pa, odakẹ bi ẹni ogbọ, o ti tọju ọfa rẹ silẹ bi ọkan ti di Ejola ti nsa re rarara bo wa si ọdọ wọn o ta a lọfa o si pada,

Nwọn wa ri ẹsun pata we mọ wọn lẹsẹ lati pa wọn, tubu ti nwọn fi wọn si ko ni aja ti o dara. nigbati Ogbojuleogun ribi gba jade ni o ko kunku agbado,

Awọn Inaki pe ara wọn jọ, nwọn ni iru ẹgmọ kini yi awọn ko ba awọn Ijimere jẹun nwọn wa da ajẹku onjẹ nwọn si ẹnu ọna wa, nwọn nwa ija nwọn yio si ri i, nwọn mura o di ilu awọn Ijimere, lilu koto wi wọ. ti Inaki ba mu Ijimere miran ti o ba gba ninu a yagbẹ gbigb na fẹẹ. Nigbati ija yi doju rẹ tan awọn Ijimere ti gbagbe pe awọn ti mu awọn kan ni gbekun, nwọn kan nfi ẹsẹ lọkọkan ni. Eyi jẹki awọn ọmọ Onilogbo ri aye fẹsẹ fẹ ẹ.

Ijọ keje ti nwọn ti rin ni nwọn tọ de Oke Alọ Ilu awọn erin. Oke yi ga tobẹ gẹẹ si ẹniti ogun ri i. Ṣugbọn ọna kan wa ni ala ilẹ awọn ọdẹ aperin lo mọ ọna na Bi awọn ẹgbọn rẹ ti ngmi hẹlẹhẹlẹ ti nwọn nronu ọna ti nwọn yio gba gun oke giga yi, Ogbojuleogun bu sẹrin o ni ọwọ Ọmọde ko to pẹẹpẹ, ti agba ko si wọ keregbe" (toto ṣe bi owe o) oni aja ilẹ ni awọn o bade oke alọ, ki i ṣe pe awọn yio gun un.

Ogbojuleogun bẹrẹ si pe le ni oruko iwaṣe oni, "Iwọ Ilẹ ohu, alapio ka, atẹrẹsẹ kaiye, a je igba enia ma wu kọ ara rẹ lati da enia, inu rẹ ni a o tun pada si ko si ohun ti o ko le da, ko si si ohun ti ko le gbemi, Iwọ Ilẹ ohu lanu ki a kọja, ki o to wi bayi tan, Ilẹ lanu ha ni nwọn ba kọja ninu rẹ Ilẹ si pade mọ wọn,

Nwọn rin to ibusọ mẹwa ninu ibo yi ki nwọn lọ yọ si Oke-Alọ nigbati awọn Ẹrin foju kan Ogbojuleogun wọn mura lati pada, nitori pe nwọn mọ pe ọdẹ Aperin ni ati pe ohun ti o ba wa ko dara sugbọn kan ninu wọn yi jẹ Ọlọbọn, o ni ki o lo da sẹriya fun enia o yẹ ki a gbọ tẹnu rẹ. O ni Ẹyin ọrẹ mi ọna wo ni ẹgba dehin ? kini ẹ si wa ṣe nihin ? Ẹ wi fun mi ki ngbo.

Ogbojuleogun ni awọn nlọ si ilu Ajiran ni ko si si ọna miran li awọn le gba kọja bi ko ṣe ọna yi lọ. Awọn Erin ni bi gbogbo enia tilẹ nlọ ni alafia Ogbojuleogun ko ni lọ nitoripe ohun ti o nfi oju awọn ri ninu igbo ko dara.

Ni kukuru, ki Ogbojuleogun to fa ọsa rẹ yọ okan ninu awọn ẹranko ti fi ọwọ ya rẹ gba a soke, o fẹfina pa mọlẹ Ogbojuleogun ri pe agbara on pin o kepe Ayunọrunbọ fun iran 1 wọ o ni Ayunorunbọ o ? Ayunọrunbọ o !! Ẹiyẹ buburu ti ti i jẹ lawujọ ajẹ Erin fẹ pa on o Ayunorunbọ gbere sọ lorun lohun,, onfo bọ bi ẹyiẹ, bi o ti nbọ bẹ ni ara nsan, ti manamana nkan yẹri Awọn Erin ko gbọ iru ro lile bayi ri eyi mu ki Olukuluku wọn salọ nigbati awọn Erin sa lọ tan nwọn ko mọ ọna na Ayunọrunbọ saju oni ki nwọn tẹle on yi yọ ti nwọn ma yọ, o di Ọjọ keji ilu Alọ ni nwọn vo si bi nwọn ti fẹẹ ma dupẹ lọwọ Ayunọrunbọ lo ba pora mọ wọn loju owa su wọn suu, Ogbojuleogun wa wa.

Oh a ọkunrin jẹ patapata O ni iya ti ọna Ajiran yi to gẹ ẹ, ihin ni on yio kusi,

Ọkan ninu awọn ẹgbọn rẹ bẹrẹ si rẹrin, oni, Ogbojuleogun aburo mi ọwọn, ọmọde ni ọ lo titọ, o ni ogun ja a arọni, lọ, Ọdẹ aperin ni ọ, o si ti ṣe akapo arọni fun ọdun jọjọ, Ṣugbọn ko si bi omode o tilẹ se to, ki o ma huwa ọmọde, nigbati o ni ki a pada nihin, Ireh n kini ki a mu pada lọ fun awọn ara ile? ọrọ na yio wadi o nlọ ile ko dele, o nlọ oko ko dako nitorina ni owurọ ọla hei, a o mu ọna Irin ajo wa pọn. Okuta ki saisan, ẹni kẹni ninu wa ko ni samodi ọrọ iṣiri yi tun mu ọkan Ogbojuleogun le, o ni o ya "bi o tilẹ jẹ oju" ina on yio lọ,

Irin Ajo ti ọtẹ yi wa le gan an, nitoripe wọn yio gba ilu awọn Ẹkun, kini wọn ati ejo kọja, Ogbojuleogun ni ki awọn ẹgbọn rẹ jo ko ki wọn ṣe aṣaro lori ọrọ bi nwọn o ti ṣe kọja ni ilu wọn yi lai ri ifarapa. Nwọn joko, Ojo daun o ni aṣaro kan ko tuo si mọ. Ayunọrunbọ san an ni awọn yio pe ko kuku tẹle wọn lati le ba ewu yi ja, nwọn ko ja ara wọn ni iyan rara, Nwọn pe Ayunọrunbọ. o yọ si wọn nwọn ko ẹdun ọkan wọn nwọn sọ fun un, on, ki wọn ma atẹle on, nwọn bẹrẹsi tẹlee, bi ere bi awada bi ere bi awada wọn yọ si Ilu awọn Kiniwun.

Gẹgẹ bi ẹnyin na ti mọ, ko si ẹda to le woju kinni wun ki o ma lọ rara. Sugbọn o ti kilọ fun wọn pe ki nwọn mase bẹru ko si ohun ti awọn kiniwun na yio se fun wọn ti nwọn ba tẹle on sugbọn ewo rẹ, ni ki wọn ma wo ẹhin ẹniti o ba wẹhin rara bẹni ẹran yio mu u, bin wọn ti okọja lọ larin awọn kiniwun yi ni nwọn nfẹja mọ wọn sugbọn nwọn ko wẹhin rara bẹni nwọn ṣe kọja lairi ifarapa Bakanna ni nwọn koja ri ilu awọn Ẹkun, Ogidan Ọlala iju, ifarapa ko si fun wọn,

Nigbati wọn de ilu awọn ejo aiya wọn ja nitoripe awọn ejo oloro bi iko, ọṣa Oloyọnbẹrẹ paramọlẹ abawere, ọka ṣebe agbadu ko ara wọn jọ nwọn fori kori nwọn wa dabi ewe runmọ, nwọn ko fi alafo ọna silẹ lati kọja afi eniti yio tẹ wọn mọlẹ li ole gba ilu yi kọja Ojola paapa wa duro lẹnu bode, o naro patapata o nṣọ eniti yio kọja riri ti awọn ti awọn Ọmọ onilogbo ri Ojola yi nse ni nwọn bu u ẹlẹ nwọn ba egun ti Ayunọrunbọ ṣe fun wọn jẹ nihin ni Ojola ti gba ya wọn ku diẹ ki o mu wọn ogbojuleogun taa lọfa o si pa. lairi Ikan kọja ni ilu awọn Ekun Ogun Ọlọla iju, ifarapa ko si fun wọn,

Nigbati wọn de ilu awọn ejo aiya wọn ja nitoripe awon ejo oloro bi iko ọsa Oloyonbẹre iranlowo ki oto yo si won o fun won ni ohun jijẹ ati mimu o tun ni ki nwon tẹlẹ on

# Ọga ọlọpa Rọ Awọn Enia Ọyọ Lati Se Suru

Igbakeji ọga Ọlọpa ni ẹkun Ọyọ Ọgbẹni J.O Pogoson si rọ gbogbo awọn oselu ẹkun na lati se suru ati lati le jẹ ki isi ọkan balẹ ni ẹkun na.

Nipa eyi, Ọgbẹni Pogoson si kilọ fun ọmọ ẹgbẹ oselu lati sọra gidigidi nipa ki kegbe ninu ẹrọ gbohungbohun ati lati sọra nipa kiko ohun ọsẹ sinu mọto nwọn

Ọgbẹni Pogoson se ikede eyi nigbati o ba awọn ọmọ ẹgbẹ oselu ti Afẹnifẹre, Alakukọ ati Dẹmọ(NNDP) se ipade laipẹ yi

Ọga Ọlọpa na si tunfi ye awọn ẹgbẹ oselu na nipa iwa janduku ti nwọn si nhu ti o si fi ye wọn pe ko ohun rere wa ati pe ti nwọn ko ba tete dẹkun si iwa bẹ oni ijọba rere ati ofin to rọrun ko le fi idi mulẹ ni agbegbe na.

Ọgbẹni Pogoson si fi ye olukuluku pe awọn ọlọpa yio ma rin kakiri ati pe eniti nwọn ba ri pẹlu iwa bẹ pe awọn yio se ohun to tọ pelu rẹ.

Awọn enia to jẹ asoju fun awọn ẹgbẹ oselu na si se ileri fun ọga Ọlọpa na pe iwa iru bẹ ko ni waiye mọ.

## Gomina Iwọ Orun se abẹwo Ile Isẹ Yaba

IKẸJA awọn Oludari isẹ ti nwọn ti nse Taya Moto ati Kẹkẹ Ologere ti orukọ nwọn njẹ (Dunlop Tyre Factory) si ti ngbinyanju lati le se ọpọlọpọ Taya ti yio to fun lilo fun awọn enia ile wa ati pe awọn ẹgbẹ osẹ na si ti se apa mẹta ninu isẹ ti Taya sise na.

Eleyi jade nigbati Oludari isẹ ile isẹ na Ọgbẹni Ain Propter fi ye Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun Ọlọla Ọdẹlẹyẹ Fadahunsi nigbati o nse abẹwo ile isẹ na laipẹ yi ni Ikẹja

Ọgbẹni Propter si tun si yẹ ọlọla Fadahunsi pe egbẹwa toun ji rọba ti ilẹ Naijiria ni awọn siti lati pe diẹ lati ilẹ okere ni awọn si nlọ fun isẹ Taya na.

Oludari isẹ na si tun fi ye Gomina na pe owo tabua bi £3, ooo, ooo ni nwọn si fi kọ ile isẹ na ati pe awọn si gba ẹgbẹta awọn ọmọ ilẹ Naijiria lati sisẹ ni ile isẹ na ati pe £150,000) ni ile isẹ na si nsan fun awọn ijọba apapọ un owo ibode.

Awọn Taya ti nwọn nse ni ile isẹ na si jẹ fun mọto ayọkẹlẹ, mọto akero ati fun awọn Taya kẹkẹ lati lo ni Naijiria ati papa fun ilẹ Ghana.

## Ikede Fun Awọn Ọmọ ile Iwe

Ọmidan Bọsẹde Olufunmilayọ Shoyinka ọmọ opitan Ajiran ilu oku yio bẹrẹsi fi Itan Aladun, Alọ ati Owe da yin lara ya ni ojojumọ ninu iwe Irohin Imọlẹ Irohin ko to afojuba ẹnyin ọmọ ile iwe ẹ mase jafara lati maa ra Irohin Imọlẹ.

Olotu

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan. 20-Feb. 18) Bi nwọn ba fa ọ sẹhin ni ipo mase da wọn lohun, nse ni ki o joko silẹ, ọrẹ iwọ pẹlu olufẹ rẹ yio pọ loni, sọra mase na inakun

PISCES (Feb. 19-Marich 20) Odabi wipe ohun ti o ngba lero suwọn, iwọ o si ri pe, anfani ni nkan na yio jẹ, ohun ti ọgbọn ori re fi ye ọ ni ki o tẹle

ARIES (March 21-April 19) Oni ni ọjọ ti o dara fun nkan ti ara rẹ, ko si dara ki o tun yẹ si gba miran mọ, tun ara rẹ se niwaju awọn ti o fẹ ki o ma sise si ija

TAURUS (April 20 May 20) Dahun si awọn ọrọ pataki to mibẹ nilẹ tọkan-tọkan, owo ati arisiki yio si ma ba ọ jẹ

GEMINI (May 21-June 21) Ija kan yio sẹlẹ nisakani ọdọ rẹ lo aiyederu ọna lati fi se ẹsin ọrọ rẹ on lo dara fun ẹsan.

CANCER (June 22-July 22) Ire yio ma de si ọ lọtun losi ninu isẹ rẹ, sugbọn mase lo asiko danu nipa lilepa ohun ti ko ni di.

LEO (July 23 - Aug 22) Eyi ni akoko ti a le fi pari ọrọ yi kan ti o ti mbẹ nilẹ ki omiran ma ba sẹlẹ Awọn ọmọ rẹ, baba, iya ati iyawo rẹ yio mu inu rẹ dun loni, lo ki ọrẹ rẹ atijọ ki o si ma lọ kesi.

VIRGO (Aug 23 - Sept 22) Ti alafia ara rẹ ni ki o kọkọ gbọ, awọn ọrọ pataki nikan ni ki o kọkọ gbọ na sọra mase ko ẹgbẹkegbẹ

LIBRA (Sept 23 - Oct 23) Ọjọ ire ni oni, jẹ fun ọ lotun losi fun gbogbo ire awọn ẹbi rẹ yio fi tọkantọkan iwọ o si ma te siwaju, ninu ohun rere gbogbo ori tiẹ dara lati lọ se abẹwọ

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22) Ilọsiwaju yio wa ninu isẹ rẹ, ... iwọ o si ma ri ere jẹ lọnakọna, pari ọrọ owo kan ti o ti n... ija sile larin iwọ pẹlu ẹnikan

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec) Oni lọjọ to dara lati pari awọn ija kekeke ti o mbẹ nilẹ, sugbọn ko lo ọgbọn si ti awọn to sunmọ ọ, ko ... a le pari tan patapata Iwọ yio ri ol inr n t tun fẹ.

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 19) Nigbati o ba di ni akoko ọsan arẹ yio lẹ mu ọ mase dahun si ipe kan ti nwọn o pe ọ, ki o si roo wo daradara ti o ba tọ bẹ.

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIKI

ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan isẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala sisẹsẹ ti o kọ le jeun daradara, tabi ki o male sun dada ọkun lọsan tabi loru tabi awọn isan ara rẹ gbogbo ki se fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn isẹ tabi wahala sisẹ tabi fun awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jube lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba y'Arẹ" nigbakugba yio salọ pelu igoaba-dun ati alafia diro de ọ. Iyen daju Bere Egbogi na ni Sọbu awọn

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos

# Agba Kosi, Ilu Bajẹ

Lati Ọwọ ALHAJI Y. A, DISU

**Lowe lowe ni awọn agba, a ni agbalagba atijọ ma a nsọtọ, Owe si ni ẹsin ọrọ, Bi ọrọ ba si sọnu, owe ni nwọn fi nwa a, Mo bẹ ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ ẹ farabalẹ, ẹ ka ọrọ mi yi lakaye, Ẹ ka owe mi yi lakaye AGBA KO SI, ILU BAJẸ, BAALE ILE KU, ILE DI AHORO.**



ALHAJI Y, A, DISU

Ọrọ pọ ninu owe yi, Ẹni ti o ba si ka a lakaye, yio ri i pe o kun fun ọgbọn ati laakaye yin si ri ẹkọ gidi kọ nibẹ Ọpọlọpọ owe Yoruba ni o si ma a kun fun ọgbọn ati laakaye, Onila, kaye si ni ẹrọ mba wa

Ki Eledumare maṣe ṣe wa ni alaibọ laakaye

Kj Odumare gba adura awọn onkọw at awn onkawe tabi gb jiujọ iwe Irohin Imọlẹ ledula,

Ki O fun wa ni laakaye ti o pe perepere Ṣẹgẹbi ti Anabi Mohammed (salalau-wasalam) ati bi,

O si ti ṣe fun Anabi yisa Alehinsalam ni laakaye ati bi o si ti ṣe fun gbogbo awọn Anabi rẹ ni lẹkun aakaye Amin o

Bi owe Agba kosi——ti e ṣẹlẹ niyi o. Ni akoko kan, ọjọ na ti pẹ jọjọ, Baba kan wa, gbajumọ pupọ ni baba na, Ẹni ire ati olokiki enia si ni Ni gbogbo ọna ni baba na na si fi yaayi, O ni aya pupọ o si bi awọn ọmọ pupọ Baba na dagba o si darugbo ki o to lọ jẹpe Ọlọrun Lati ọjọ ti o ti ku titi ti o fi di ogoji, ọjọ ni awọn ọmọ rẹ ti npa malu abọra lojojumọ, nwọn si nṣe, nwọn si nsọ Ẹsẹ awọn ijoye, olowo ati borọkini ni o si pe ṣọṣọ si ibi aṣeye isinku na Irohin ko to afojuba ni aṣeyẹ na'

Ilnu awọn ọmọkuurin ti o ogbe na bi ọdọ mẹrin mbẹ ninu wọn, Meji ninu wọn si jẹ oye olori awọn ẹgbẹ awọn olokiki kan ni lu wọn ti o ni okiki pupọ Meji yoku si jẹ pataki ninu Ẹgbẹ olowo kan.

Gẹgẹbi akọsilẹ olukuluku awọn opo mẹrẹrin ọmọ baba olokiki na si lọ jẹ ipe Ọlọrun,
ni ṣiṣẹ ntẹle lẹhinti baba wọn ti di ologbe ni nkan bi ọdun mẹwa sẹhin,

Ki si nwọn ro ku nwọn mu ile baba wọn dani dada uwọn ko jẹ ki okun alajọbi ti ọwọ wọn ja

Nwọn si gbin ifẹ ododo sinu awọn mọlẹbi nwọn ran ara wọn lọwọ nwọn si jijọ nṣe aju mosepọ pẹlu gidi,



## Ikede Fun Awọn Ọmọ Ile Iwe

Ọmidan Bọṣẹde Olufunmilayọ Shoyinka ọmọ opitan Ajiran ilu oku yio bẹrẹsi fi Itan Aladun, Alọ ati Owe da yin lara ya ni ojojumọ ninu iwe Irohin Imọlẹ Irohin ko to afojuba ẹnyin ọmọ ile iwe ẹ maṣe jafara lati maa ra Irohin Imọlẹ.

Olotu.

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TONIKI

ALE-BI-ELE Egbogi Toniki Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala ṣiṣẹṣẹ ti o kọ le jẹun daradara, tabi ki o male ṣun da-da ọkun lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala ṣiṣẹ tabi fun awọn alera gbogbo nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN' ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugbẹ y'Arẹ" nigbakugba yio salọ pẹlu igbaba-dun ati alafia diro de ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbu: awọn
WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos

## Iwọ Ha Fẹ Kọ Ile Bi?

Bi o ba fẹ ra ilẹ tabi o fẹ ta ilẹ tabi boya o fẹ kọ ile.

Tete kọwe si wa fun gbogbo awọn ohun ti o ba nfẹ.

Bi o ba kọ ile, ale ma a ba ọ gba owo lọwọ awọn olugbe ile rẹ kia kia, ki owo na e si tẹ ọ lọwọ ni asiko

Tabi ti enia ba je o lowo ti ko san, kọwe si wa, were ni a o ba ogba a lowọ rẹ

Fun ẹkunrẹrẹ alaye, kọwe siwa, ki o si dan wa wo lẹ ẹ kan ṣoṣo a o si fi ohun gbogbo tẹ ọ lọrun

J.O. Shoyinka.
General Manager
1, Ishiba Street
Itirẹ—Yaba

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No, 722 THURSDAY, JUNE 18, 1964 (2D


## Awọn Onişowo Fẹ Pe Ijọba L'ẹjọ

ABA:- Gbogbo ile lo kunsọsọ ti ẹṣẹ ko si gbeji ninu Ipade ti gbogbo awọn ẹgbẹ onişowo gari şe ni ọjọ Abamẹta ti işe ọjọ ketala oşu yi ti awọn onişowo na si "nhalẹ pe, awọn yio pe Ijọba lẹjọ nitoripe awọn ti padanu ọkẹ mẹta (£60,000) pọnun lati igbati awn oşişẹ ti da işẹ silẹ.

Awọn enia na ni gbogbo ọja ti awọn ra silẹ lati ba ọkọ reluwe lọ si Ipinlẹ Ariwa ni gbogbo wọn ti bajẹ tan patapata. Ninu awọn ẹru na ni, ẹgbaa mẹrin o le Irinwo (6, 4000) apo ọgẹdẹ, agbado, apo ẹwa, apo Ila, ọsan, apo timọti eyiti iye owo wọn jẹ ẹgbẹdogun o din ọgọrun pọnun (£29, 000).

Awọn enia na sọ pe gbogbo awọn ẹru na ni o ti baja si ibiti awọn ko gbogbo wọn si nu ọgba ọkọ reluwe ti relu we ko si ko wọn lọ Nibiti awọn ti ko apo Gari na s ojo ti ba gbogbo rẹ jẹ ti ko tun şe jẹ fun ọmọ enia mọ.

Awọn onisowo na ni lati ọjọ kedogun osu karun ọdun yi ni awọn ti ko awọn ẹru kan ransẹ si Ipinlẹ Ariwa ti awọn ẹru ko si ti de ọdọ awọn enia ti awọn fi ẹru na ransẹ.

Awọn enia na wa pari ọrọ wọn pe, Bi Ijọba ko tete da osisẹ lohun ibere wọn ki awọn tete pada si ẹnu isẹ, ti aba tun sofo ẹru ti o ju eleyi lọ, ao pe ijọba lẹjọ iba ẹru ẹni jẹ.

# EGUNGUN NA OLỌPA NI ANA ŞI FILA SỌNU

IJẸBU—ODE:- Lẹnnlọlọ¡i ni awọn elegun Ijẹbu Ode nşe ọdun egungun wọn ti ọkan ninu awọn egungun na si na Ọlọpa kan ni ara şi fila sọnu nigbati Ọlọpa na rekọja ni iwaju wọn.

Irohin fi ye wa pe awọn eegun Ijebu Ode nşe are egungun wọn Şugbọn Ọlọpa na fẹ rekọja ni arin igbo ti nwọn ti nşere.

Bi awọn egungun na ti ri Ọlọpa na, ti o nbọ w si ọdọ won, ni nwọn ba sare lọ si ọdọ rẹ wipe, ki Ọlọpa na o bọ bata ẹsẹ rẹ ki o si tun şi fila ori rẹ.

Şugbọn ọkunrin na sọ fun awọn elegungun na pe, "Ọlọpa Oba ni mi, nko kan wọ aşọ Ọba lorun nisisiyi ni, nitorina mko le si fila mi"

Irohin fi ye wa pe ki Ọlọpa na to sọ bayi tan atori ti nke lara rẹ bi igbati nwọn nşe ọdun orişa Ogidan.

Lẹsẹkẹsẹ ni ẹniti a ni ki o şe to! ti o ni on ko le şe to! to!! were ni ator i şi fila Ọlọpa na ti o si tun sare tu bata rẹ nigbati atori dun un dada.

Şugbọn Ọlọpa na gbe basikulu rẹ silẹ, o si fi ipa mu egungun rẹ na de Teşan Ọlọpa lati lọ sọ ti ẹnu rẹ.

Nigbati egun na de Teşan awọn Ọlọpa, "egungun di enia" ni Teşan, ariwo si ta ge e! pe, ah! a şe iwọ ni?

Lẹhin eyi ni nwọn ba gbe ẹjọ na lọ siwaju adajọ fun ayẹwo. Nigbati ẹjọ na de Ile ẹjọ Adajọ yẹ gbigbọ ẹjọ na si ọjọ Ẹti ti işe ọjọ kejila oşu yi.

Şugbọn nigbati ẹjọ na delẹ ni ọjọ yi, ti nwọn si pe ọdaran na, Adekanmi Alamọran ẹni ọdun marundinladọta lati wa sọ ti ẹnu rẹ bi o ti şe na ọlọpa, ni ọlọpa ti se agbẹjọro Ijọba Ọgbẹni Ọlatubọsun Odukọya ba sọ fun adajọ pe nigbati odi arin ọsẹ yi ni on gbọ ti nwọn si tun wa pe on pe ọdaran na ku

Gbogbo ile ẹjọ lo ya ẹnu silẹ ti nwọn ko si le pade mọ ni ọjọ na. Lẹhin eyi ni adajọ na ba sọ fun gbogbo awọn elegungun ti nwọn wa ni ile ẹjọ na pe on ti fa igi le ẹjọ na, on si tun tuu ka.

## Ijọba Gba Lati San Ekunwo Owo Oşu Awọn Oşişẹ

Lati Oju Ewe Kini

awọn enia na, o si faramọ gbogbo ohunti Apapọ Ijọba ba şe nipa ọrọ awọn oşişẹ.

Nigbati o sọrọ tan ni Minista Alamojuto eto inawo fun Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun Naijiria wa dide ti on na si tun şe alaye ati ohunti Ijọba rẹ ngbero lat şe fun awọn oşişẹ. lẹhin ọrọ şoki o joko lori aga rẹ.

Bi o ti soro tan, ni Oloye Okotie- Eboh wa kesi Ọba C. D. Akran eniti o sọrọ ni Oruko Ijọba rẹ.

Ninu ọrọ rẹ, Ọba Akran şipẹ fun awọn Oşişẹ lati şe suuru, lori ọran ẹkunwo owo oşu ti awọn Oşişẹ nbere yi.

Ọba Akran ni ọkan ninu awọn Aşiwaju ẹgbẹ Oşişẹ ni on ti jẹ nigbakan ri ki on to de aye Minista ti on wa yi.

O tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ pe bi Ijọba ba san owo oşu ju bi o ti ye lọ fun awọn osisẹ ọja yio tun wọn lọja ju bi o ti yẹ lọ nigbati o si jẹ wipe gbogbo enia kọ lo nse isẹ labẹ ijọba, sugbọn gbogbo enia lo nra ọja.

Şugbọn ki o to sọ ọrọ na delẹ ni Alhaji Adebọla sọ fun oba Akran pe Awọn Oyinbo onisowo nlyẹn lọdọ rẹ 'o sọ fun wọn ki nwọn o mase i owo kun owo oja boya nwọn a jẹ da ọ lohun sugbọn ki Alhaji Adebọla to sọrọ na tan, ni gbogbo ile ba ku silẹ ti wọn si nrerin. Ọba Akran na rerin diẹ o si tun nba ọrọ rẹ lọ

Nigbati gbogbo wọn sọrọ tan, ni awọn Alamojuto Ijọba wa gba wipe, awọn yio san ẹkunwo owo-oşu fun awọn oşişẹ gẹgẹbi Igbimọ oluwadi Morgan ti şe sọ.

Şugbọn awọn Asiwaju ẹgbẹ oşişẹ tun fẹ ki Ijọba gba lati maa san iye owo kanna fun gbogbo oşişẹ ti wọn nşişẹ ni Eko ati awọn to nşişẹ ni Ipinlẹ gbogbo

Ijọba ko ti gba eleyi ohunti Ijọba wi ni wipe awọn ti o ba nşişẹ ni Eko ati agbegbe rẹ, o yẹ ki owo oşu wọn ga ju ti awọn ti nşişẹ ni Ipinlẹ lọ.

Awọn Asiwaju ẹgbe oşişẹ ni awọn ko fi aramọ ọrọ na Nwọn wa şe alaye pe, ti osişẹ kan ba nşişẹ ni Eko ti işẹ ba gbe lọ si Ibadan ki o wa ma a lọ gba pọnun mejọ (£8) nigbati o jẹ wipe pọnun mejila (£12) lo ngba ki o to kuro ni Eko

Lori ọrọ yi ni awọn enia na wa ti nwọn ko si le pari ọrọ na titi ti nwọn fi pari ipade wọn ni alẹ ana

Şugbọn nwọn o tun maa ba ipade na lọ ni irọlẹ yi, nibiti nwọn ba si pari ọrọ na si ẹ o maa gbọ ninu iwe wa ni ọla.







Printed and Published by Medupe Printing Press 16, Bamgbgose Street Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street, Lagos (18/6/64)